**ORÍ ÒKÈ INÁ ÀTI IṢẸ́ ÌYANU**
Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nigeria.
**ÈTÒ ÌPÀDÉ AGBÁRA GBỌ́DỌ̀ PÀRỌ̀ ỌWỌ́**

**BÍBORÍ ÌWÀ ÌKÀ ÌDÍLÉ (3)**
**OṢÙ KARUN, ỌDÚN 2025**
Ìwé Mímọ́ Kíkà: Gẹ́nẹ́sísí 4
Ìjẹ́wọ́: Lúkù 10:19

## ORIN ÌYÌN ÀTI ÌJỌ́SÌN TÍ Ó L'ÁGBÁRA

1. Ọlọ́run, dìde, kí Ó sì fàtu ohunkóhun tí O kò gbìn sínú Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
2. Ọlọ́run, jẹ́ kí iná ìṣọ́ji bàlé Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
3. Ọlọ́run, jẹ́ kí agbára àláfíà àti itẹ̀síwájú, ṣíjibo orílẹ̀-èdè yìí, ní orúkọ Jésù.
4. Ọlọ́run, dìde, fún wa ní àwọn olórí tó bẹ̀rù Ọlọ́run, ní orúkọ Jésù.
5. Mo ya iṣẹ́ àwọn ọ̀tá ìdílé lórí ọ̀rọ̀ ayé mi lárọ, ní orúkọ Jésù.
6. Mo tú ètò ìṣúná mi sílẹ̀ kúrò lábẹ́ ìmísí, ìdarí àti ìjẹgàba ìkà ìdílé, ní orúkọ Jésù.
7. Mo gba ìdúróṣinṣin mi kúrò lọ́wọ́ àwọn àjẹ́ ìdílé, ní orúkọ Jésù.
8. Àrá Ọlọ́run, ṣàwárí, kí o sì tú ìtẹ́ àjẹ́ nínú ìdílé mi ká, ní orúkọ Jésù.
9. Ọwọ́ ààbò Ọlọ́run, bàlé ayé àti ẹbí mi, ní orúkọ Jésù.
10. Olúwa, gbàmí kúrò nínú gbogbo iṣé búburú, ní orúkọ Jésù.
11. Gbogbo agbára òkùnkùn tó n fa ògo mi mu, gba ìjákulẹ̀, ní orúkọ Jésù.
12. Gbogbo ogun tó takú pé mo gbọdọ̀ gba itìjú l´ọ̀dún yìí, tapadà, ní orúkọ Jésù.
13. Mo rún lábẹ́ àtẹ́lẹsẹ̀ mi gbogbo agbára búburú tó n gbiyànjú láti fimí sínú túbú, ní orúkọ Jésù.
14. Agbára sátánì tó n gbé ìpọ́njú dìde nínú ayé mi, jórun nípa iná, ní orúkọ Jésù.

15. Gbogbo ìgbóguntì ọ̀tá láti dábù àwọn anfàní tó n bọ̀ lọ́dọ̀ mi, túká, ní orúkọ Jésù.
16. Olúwa, fún mi ní ìṣẹ́gun lákokò tó yẹ lórí ipò mi, ní orúkọ Jésù.
17. Aṣọ àkísà lára mí, tó n jẹ́ kí ayé nira fún mi, gb'iná, ní orúkọ Jésù.
18. Àwọn agbára tó dèmímọ́lẹ̀ sí àfonífojì, já ìdè rẹ lórí mi, ní orúkọ Jésù.
19. Àwọn agbára tí wọ́n yàn láti nà mí ní pàsán, kí wọ́n sì tún jámi síhòhò, ẹ gb'iná, ní orúkọ Jésù.
20. A-sọ-ìpọ́njú-di-púpọ̀, tó n sọni dòfo, gb'iná, ní orúkọ Jésù.
21. Ẹnubodè àjẹ́ tó tì mí sóde alàjá mi, túká, ní orúkọ Jésù.
22. Aṣọ ìparun nínú ohun-ìní mi, gb'iná, ní orúkọ Jésù.
23. Àwọn agbára tó sọ ayé mi di ibi ìjókò sátánì, ẹ gba ìparun báyìí, ní orúkọ Jésù.
24. Àwọn ẹlẹ́gàn láyiká mi, tí wọ́n kórajọ̀pọ̀ láti fàmíwálẹ̀ níwájú àwọn olùrànlọ́wọ́ mi, ẹ gba itìjú, ní orúkọ Jésù.
25. Jígí búbúrú, níbi tí wọ́n ti n dárúkọ mi fún ibi, fọ́, ní orúkọ Jésù.
26. Jígí búburú tó n tọpinpin mi, tó n ṣí ayé mi sílẹ̀ fún ewu, fọ́, ní orúkọ Jésù.
27. Àwọn agbára tí wọ́n yàn láti ṣìmí darí láti kórè ìkùnà ní bèbè alàjá, kú, ní orúkọ Jésù.
28. Àwọn àjòjì ní ilé tí mò n gbé, tí wọ́n yàn láti mú ìjákulẹ̀ bá ètò-ìṣúná mi, jó di éérú, ní orúkọ Jésù.
29. Ògo mi tí wọ́n fi pamọ́ sábẹ́ àpáta, gba ìtúsílẹ̀ nípa àrá, ní orúkọ Jésù.
30. Olúwa, dá ọwọ́ Rẹ lé mi láti túmisílẹ̀ kúrò nínú ìdè ọ̀rọ̀-ajé, ní orúkọ Jésù.
31. Agba-gbèsè òkùnkùn tí wọ́n yàn láti gba gbèsè tí nkò jẹ, gb'iná, ní orúkọ Jésù.
32. Wàhálà ètò-ìṣúná nínú ayé mi, dópin báyìí, ní orúkọ Jésù.
33. Gbogbo iṣòro tó n pe àṣeyọ́rí mi níjà, jórun nípa iná, ní orúkọ Jésù.

34. Gbogbo ọgbẹ́ nínú ọkàn mi, tíkò jẹ́ kí inú mí dùn, gba iwòsàn nípa agbára tó mbẹ nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù, ní orúkọ Jésù.
35. Gbogbo ọ̀tá ògo mi, mu omi ìkorò ègún, ní orúkọ Jésù.
36. Gbogbo ìkòkò òkùnkùn tí wọ́n fi jìn láti fa ìṣubú mi, fọ́ nípa iná, ní orúkọ Jésù.
37. Gbogbo ahọ́n tó n sọ̀rọ̀ ibi láti sọmí di ẹni yẹpẹrẹ níwájú àwọn olùrànlọ́wọ́ mi, di gígé kúrò nínú ayànmọ́ mi, ní orúkọ Jésù.
38. Ìkúùkú Ọlọ́run, bo àwọn ọ̀tá mi mọ́lẹ̀ sójúkan, ní orúkọ Jésù.
39. Ògiri òjijì, farahàn láàrín èmi àti àwọn ọ̀tá mi tó n gbiyànjú láti fàmíwálẹ̀, ní orúkọ Jésù.
40. Ẹ̀jẹ̀ Jésù, fọ ìdókówò sátánì kúrò nínú ìran ẹ̀jẹ̀ mi, ní orúkọ Jésù.